# ÀWỌN ẸTỌ́ ÀTI OJÚṢE OBÌNRIN NÍNÚ ÌṢÈLÚ GẸ́GẸ́ BÍ ỌMỌ ORÍLÉÈDÈ

BAOBAB

Ìdúpé

1. Ìfáàrà

2. Èdè Àmúlò

3. Agbékalè Àwon Òfin tí ó níse pèlú kíkópa àwon obìnrin nínú ìs èlú

3.1 Ofin ìsèlú Ilè Nàìjíríà

3.2 Àgbékalè Àjo ilè Áfíríkà Lórí Ètó Omonìyàn

3.3 Àgbékalè Ètó Omònìyàn Lóde Àgbáyé

3.4 Àdéhùn Òde-Àgbáyé lórí Ètó Ìsèlú àti Ètó Omonìyàn

3.5 Ìpàdé Lórí Pípa Onírúurú Ìdéyesí - àwon obìnrin Ré

4 Ìkópa Àti Ojúse Àwon Obìnrin Nínú Ìsèlú

4.1 Ojúse láti Díbo fún-ni àti Láti Gbápòótí Ìbò

4.2 Yíyan Olùdíje-ìbò

4.3 Ìlànà bí a se ń Dìbò

4.4 Ètó Àwon obìnrin Nínú Egbé Òsèlú

5 Àwon Ìpèníjà tó Dojú ko Àwon Obìnrin Nípasè kíkópa Nínú Ìs èlú

5.1 Àwon Ìdíwó Tó je mó Èrò inú Àsà

5.2 Àwon Ìdíwó Tó je mó Ètò Orò-ajé

5.3 Àwon Ìdíwó Tó je mó Ètò Àwùjo

5.4 Àgbékalè Ìlànà àti Àdáwólé orílèèdè

6 Ònà Àbáyo fún àwon ìpèníjà tí a ti ménu bá

7 Ìkádìí

# Ìdúpé

A kò lè so pé a ti se àseyorí lórí ìpèsè ìwé-ìléwó yìí láìjé wi pé a fi èmí ìmoore wa hàn sí àwon elégbé wa bí mélòó kan fún ipa ribiribi tí wón kó nípa fífi àkókò àti ara won sílè lófèé.

Kìí se wí pe a fé to orúko àwon ènìyàn won yìí gégé bí ipa tí won kó se lówúra sí sùgbón a kókó fé gbé sàdańkátà fún Òmòwé Abubakar Momoh tí Fásiti Ìpínlè Èkó fún aáyan rè. Ipa tí ó kó yìí sàfihan rè gégé bí olópolo pípé èdá nídìí òrò èkó ajemó-òsèlú. O pé tún ye Fúnke aya Táíwò - eni tí ó jé ògbóǹtagí olósèlú àti òkan lára àwon omo egbé yìí tí ń se gudugudu méje àti yààyàà méfà ní ìlú Èkó. Ògbéni Obo Effong náà seun nítorí wí pé a ń rí ogbón àti ìrírí rè sàmúlò ni òpòlopò ìgbà. Bákan náà, a dúpé lówó Òmò wé Victoria Adidu tí ó jé alákòóso àjo BAOBAB yìí ní ìpinlè Kàdúná àti Ògbéni Ibrahim Khaleel Abudssalam tí òun wà ní ìpínlè Káno ní tirè.

Ìwé Ìléwó yìí kì bá tí le wáyé bí kò bá sí ìrànlówó owó tí àwon ìgbìmò Transistion Monitoring Group (TMG) pèsè. A sì tún nílati fi èmí ìmoore wa hàn fún ìyòǹda tí TMG yìí fún wa láti jé kí a dágbálé pípèsè ìwé-Ìléwó yìí. Ìwé ìléwó yìí je èso aáyan àti ìlàkàkà wa fún ìpolongo ìgbéláruge ìkópa àwon obìnrin nínú ìsèlú.

Lákòótán, a fé dúpé lówó gbogbo àwon òré àti ojúlùmò wa tí a

jo ń sàkitiyan láti rí i wí pé ètó àwon obìnrin kò di àtèmérè láwùjo. Àwon ni won ń fi okun kún okun wa nípase onírúurú ìwé tí won fi n sowo sí wa àti ìgbani-níyànjú won lóòrè-kòòrè.

A mo rírì Àjo John D àti Catherine T. MacArthur àti Ajo Ford pèlú fún ìrànlówó owó ní gbogbo ìgbà. Opélopé won lara wa. A dúpé fún ìbásepò won.

**Àwon omo ìgbìmò ìwé yìí:**

Onàadé Òjó

Sindi Médar-Gould

Chibogu Obinwa

Olúbùnmi Dípò-Salami

## Ìfáárá

Bí ó tilè jé wí pé iye àwon obìnrin tí ó wà ni oríléèdè ilè Naìjíríà kò dín ní ìdá àádóta nínú ogórùn-ún bí a bá sàfiwé iye won pèlú iye àwon okùnrin, síbè, won kò jàǹfààní ètó omo oríléédè àti ìsèlú ilè yìí lékùn-ún réré. Èyí sì tako òpòlopò àdéhùn àjo àgbáyé tí ilè Nàìjíríà náà fowó sí. Oríléèdè ilè Nàìjíríà kò ko ibi ara sí àmúlò àti igbé-agbára wo àwon àdéhùn náà rárá. Kí àwon àdéhùn wònyí tó lè wúlò fún ìgbé-ayé àwon obìnrin ilè yìí, a gbó dò sàmúlò àwon àdéhùn náà, kí a sì mú won se.

Ìpinnu tí ó wáyé léhìn àpérò ìlú Beijing, èyí tí ile Naijiria náà fo wó sí sàgbékalè ìlànà mímú kí àwon obìnrin bí ìdá-ogbòn nínú o górun-un, ó kéré tán, máa dipò mú nínú ètò ìsèjoba. Èyí ni yóò je nǹkan ìwúrí fún àwon obìnrin láti kópa ninú ìsèlú àti ètò ìsàkóso oriléédè. Títí di òní, èyí kò tíì ri béè ni ilè Naijiria. Ohun tí ó sì fà á ni àìtíì sàmúlò ìpinnu àti àgbékalè tó ní se pèlú ètó àwon obìnrin ní ilè wa.

Títí di odún 1979, ogunlógò àwon obìnrin láti apa ìhà àríwá ilè Nàìjíríà ni kìí létòó láti dìbò yan eni tí ó wù wón sí ipò asèjoba. Ìtókasí wà pé kò sí ìlànà kan gbòógì saájú ìgbà òmìnira àti léhìn o dún omìnira nípa bi àwon obìnrin se ń kópa tó nínú ìsèlú ilè Naijiria. Láyé ìjoba Oloógun, pàápàá jùlo; láyé ìjoba Babangida, igbá kejì gómìnà méjì péré ló jé obìnrin ní ilè Nàìjíríìà. Àwon ìjo

ba tí o tèlé ti Babngida yìí kò tíì fi gbogbo ara gbé ìgbésè akin lórí mímú ki àwon obinrin kópa tó jojú nínú ìsèlú àti ìsèjoba.

Bí àwon obìnrin tí ó ń dìbò ti pò tó, bí won sì ti se ń kó ipa ribiribi tó lásìkò ìpolongo ìbò, àti àbájáde ìpinnu onírúurú ìpàdé tó je mó ìgbéláruge ipò àwon obìnrin láwùjo, àwon obìnrin kò tíì ní ìjókòó tó tó ìdá ògbón nínú ogórun-un gégé bí ìjókòó tiwon nínu ìgbìmò àti ìsèjoba. Àkíyèsí mìíràn tún ni wí pé àìdógba tí ó gbòòrò ló wà láàrin àwon okùnrin àti àwon obìnrin. Ìgbékalè àwùjo àti ètò ìsèlú ló sì fa èyí. Sùgbón sá, bí ó ti lè jé wí pé ilè Naijiria kò tíì sàmúlò àbájádé ìpinnú ìpàdé Beijing titi di asìkò yìí, gúúsù ilè Afrika ti se ìgbéláruge sísàmúlò obìnrin tí ó tó ìdá mérìndínlógójì nínú ogórùn-ún nínú èto ìsèjoba ní tiwon. Ní sáà òsèlú 1999-2003, nínú òtà-lé-lóòdúnrún (360) omo ilé ìgbìmò àsòfin àpapò, méjìlá péré ló je obìnrin. Méta sì ni iye obìnrin tí ó wà nínú àwon omo ìgbìmò asojú-sòfin àgbà nínú àpapò omo ìgbìmò tí ó jé mókàn-dín-láàdófà (109). Iyé àwon obìnrin tí a ménuba yìí fi ipò àìbójúmú tí bí àwon obìnrin se ń sojú-sòfin hàn. Irú ìkómérè nídìí ètò ìsojú-sòfin yìí náà ló ran àìka-obìnrin-sí nídìí ìyan-nisípò nínú ìsèjoba àti nínú orísìí ìpinnu síse mìíràn làárin àwùjo. Ohun tí ìwé-ìléwó yìí wá dá lé lórí ni wí pé a wo àwon abala ètó ìsèlú àti ojúse tí àwon obìnrin ni. A tún wo àwon èdè àmúlò nídìí òrò òsèlú, léyìn èyí ni a wá ye àwon òfin tó tí àwon ètó àti ojúse wònyí léyìn wò. Ojú dúdú nídìí òrò-òsèlú wà lára ìsòro tí ó dojú kó ìkópa àwon obìnrin nínú ìsèlú. Èyí ló sì fà

á tí ìwé yìí fi sàfihàn àwon ètó tí àwon obìnrin ní lábé òfin láti kópa nínú ètò ìsèlú. A tún sàyèwò ìwúlò irú ìkópa béè láàrin àwùjo.

Láti baà dí àlàfó tí ó wà lààrin ìkópa àwon okùnrin àti tobìnrin nídìí òrò ètò ìpinnu síse àti nínú òrò ìsèlú, a tóka sí àwon ìpèníjà kan tí ó dójú ko àwon obìnrin gégé bí ipò won se rí. Ohun tí ó je àfojúsùn tí ó je wá lógún jù ni bí a se lé sàwárí ogbón tí yóò kápá àìdógba tí ó wà láàrin okùnrin àti obìnrin nídìí òrò ètò tí ó je mó kíkópa nínú ìpinnu síse.

## 2. Àwon Èdè Àmúlò

Àwon èdè kan wà tí a sáábà máa ń sàmúlò nínú òrò òsèlú. Kìí se gbogbo rè ni a le ménu bà tán níhìn-ín yìí sùgbón àwon tí a sàmúlò nínú iwé-ìléwó yìí nì a tò sí ìsàlè yìí:

- **Ìjé-omo-Oríléèdè:** Omo oríléèdè ni eni yòówù ó jé tí ó bá wà ni oríléèdè kan nípa ìbí rè, nípa pé ó mòn-ón-mò so ara rè di mo oríléèdè béè lábè òfin tàbí pé ó forúko sílè láti di omo oríléèdè náà. Irú eni béè ni gbogbo ètó àwùjo àti ti òsèlú. Ó sì tún ni àwon ojúse láti máa se sí oríléèdè náà.

- **Ìrìnkè-rindò:** Èyí ni ètó gbogbo omo ilè Nàìjíríà làti le sàtìpó tàbí lo sí ibi yóòwù tí ó bá fé láti lo láì ni idíwó rárá.

- **Àwon Ètó:** Àmúye omo oríléèdè kòòkan tó ní lábé òfin, àfi ìgbà tí ó bá hùwà tí ó lòdì sí òfin ni yóò tó pàdánù irú àmúye béè. (Bí àpeere, ìjoba le gba ètó láti dìbò fún ni tàbí láti dìbò fún lówó eni tí ilé-ejo bá ti pè ní òdaràn rí)

- **Àwon Ojúse:** Isé tí n be níwáju omo oríléèdè kòòkan sí ìlú, àwùjo àti sí ara rè.

- **Ìkópa nínú Ìsèlú:** Lílówó sí ètò ìsèlú bèrè láti ibi ìforúko-sílè fún ètò ìdíbò, idibo gan-an fúnra rè, dídarapò mó egbé òsèlù,

gbígbápòòtí ìbò, fífara-mó egbé òsèlú tábí eni tí ó gbápòòtí ìbò àti dídá àwon èniyàn lékòó nípa ètò ìdìbò.

- **Ètó Ìdìbò:** Èyí ni ètó láti gbápòòti ìbò tàbí láti dìbò fún e lòmiíràn.

- **Àìlétòó-ìdìbò:** Èyí ni dídù ní ètó láti gbapòòtí ìbò tàbí láti dìbò fún elòmiíràn.

- **Ìsèlú:** Èyí ni ìgbésè fifi ìbò yan ni sí ipò apàse àti asè-pinnu fún ará ìlú pelu bi a ti se n se àkóso ètò ilu.

- **Egbé Òsèlú:** Àgbáríjopò àwon omo oríléèdè tí won ko ara jopò láti fi ìbò gba agbára ìsèlú. Àwon egbé béè yòó fa àwon àyànfé inú egbé won kalè láti díje fún onírúurú ipò pèlú èròngbà láti di asíwájú nínú ètò ìsèjoba. Wón a máa bèèrè lówó àwon omo oríléèdè pé kí wón dìbò fún egbé àwon láti baà ráyè jé kí ètò ìsàkóso ìjoba bó sí owó àwon. Egbé òsèlú gbódò ní òfin egbé àti àlàkalè àfojúsùn egbé won.

- **Ìgbágbára-Ìsèlú-Woni:** Ìgbésè tokùnrin-tobìnrin láti sè-pinnu àyànfé tí yóò sojú won kí irú asoju béè báà ráye kópa nínú ìsèjo ba. Ìgbágbára-ìsèlú-woni tún túmò sí ètó ìjoba tiwa-n-tiwa tí yóò mú ni ráyè dé àwon ilé-isé ìjoba láti pèsè àǹfààní tí yóò mú ìgbé-ayé derùn fún àwon obìnrin, àwon omodé àti àwon èniyàn àwùjo

mìíràn; yálà nípasè isé àdáse teni kòòkan won ni o tàbí èyí tí ó je mó tará ìlú lápapò.

- **Ìtanijí-sí ìsèlú:** Èyí ni ìgbésè tí a sàmúlò láti mú kí àwon ara ìlú nífèé sí ìsèlú àti láti mú kí wón sàtìléyìn fún àfojúsùn egbé òsèlú kàn níretí àti-baà jé kí egbé òsèlú béè ráyè di asèjoba.

- **Omo Egbé Òsèlú:** Eni tí ó ní káàdì omo egbé òsèlú lówó tí a lè dìbò fún, tí òun náà sì lè dìbò fún ni yálà ìbò inú egbé tàbí tí ìsèlú. Kí obìnrin yòówù tó létòó sí gbígbápòòtí ìbò wolé sí ipò ìsàkóso, irú eni béè gbódò jé omo egbé òsèlú kan pàtò.

- **Yíyege lati Díje ìbò:** Eni tí yóò yége láti díje ìbò gbódò dàgbà lójó orí láti se béè. (èyí wà lówó irú ipò tó ń díje fún), ó gbódò kàwé dójú-àmì (ibi ti yóò kàwé dé wà nínú ìwé òfin ajemó-ètò ìdìbò), ó gbódò jé omo egbé òsèlú, ó gbódò jé olùgbé agbègbè ibi tó ti fé dìbò tàbi díje. Kò sì gbodò ní àkosílè ìwà òdaràn tàbí kí won ti rán an léwòn rí.

- **Àmúye fún Ìdíje ìbò:** gbogbo omo oríléèdè Nàìjíríà, yálà o kùnrin tàbí obìnrin, olówó tàbí mèkúnnù; láìfi ti èyà rè se, ni ó lé tòó átifibò díje fún ipo yóòwú ó jé bí onítòhún bá sá ti:

1. jé omo egbé òsèlú kan pàtó
2. kàwé, ó kéré tán, dé ilé èkó girama àgbà tàbí gba

ìwé èrí mìíràn tí ó fara pé e

3. dàgbà dé irú ipò tó ń díje fún; lópò ìgbà, odún méèdógbòn sí odún márùn-ún dín-lógójì ni odún tó kéré jù fún olùdíje yòówù ó jé, èyí wà lówó irú ipò tí onítòhùn bá ń díje fún.

Iwé òfin ìsèlú ilè Nàìjíríà sàlàyé "ìwé èrí ilé èkó girama àgbà tàbí ìwé èrí mìíràn tí ó fara pé e" nínú iwe-òfin 318(1) báyìí pé;

- ìwé èrí tí a gbà jáde ni ilé èkó girama àgba
- ìwé èrí olùkóni onípò-kejì
- ìwé èrí àwon akósé-mósé *City and Guilds*
- kíkàwé dé ibi ti a ti lè sèdánwò wàyéékì.

Eni tí ó bá ní ìwé èrí ilé-ìwé alákòóbèrè nìkan sùgbón tí ó ti sisé fún ìwon odún méwàá tàbí tí ó ti kékòó àgbélégboyè mìíràn tí ó sì gbà á to odún kan náà jé ìtéwógbà lódò àwon àjo, elétò ìdìbò gégé bí olùdíje ìbò fún ìsèjoba. Ní àfikún, bí onítòhún bá mò-ón-ko-mò-ón-kà tí ó sì le báni-sòrò ní ede Gèésì, a jé wí pé àjo elétò ìdìbò yóò ka irú eni béè kún olújide tí ó kúnjú òsùwòn. Olùdíje tí ó bá níwe èrí mìíràn tí àjo olùdíbò bá sá ti gbà wolé yege láti díje ìbò sí ipò yòówù tí ó bá fé.

- **Áfojùsùn Egbé:** Àlàkalè ohun tí egbé sèlérí lati se, èròǹgbà tàbí àníyàn won bí won bá mókè léhìn ìdìbò.

- **Ìpolongo Egbé:** Ìgbésè fífi ààlò tóka sí ohun tí egbé duró fún lónà àtibaà ráyè mú ìyípada rere bá àwùjo.

- **Àwíìyànnu Egbé:** Ìgbésè mímú kí àwon ara ìlú jí gìrì sí isé ìlú.

- **Májèé-ó-bàjé:** Àwon òpómúléró inú egbé tí won ń làkàkà láti sàgbékalè àti láti sàmúlò ìpinnu fún egbé. Púpò àwon ìgbésè ti ìjoba ń gbé kò sèyìn àwon òpómúléró inú egbé wònyí.

- **Ìpàdé Gbogbo-gbòò Egbé:** Àkójopò àwon asojú tí wón kórajopò fún àwon ìdí pàtàkì kan lásìkò tí egbé ń polongo ìbò ló wó.

- **Ìbo Kòmesè-ó-yo:** Ìbò tí a dì láarin egbé láti mo àyànfé omo egbé nínú ogunlógò àwon ènìyàn tó yojú láti díje.

- **Asojú Egbé:** Eni tí ó dúró gégé bí asójú egbé kan ni àsìkò tí ìbò ń lo lówó ki wón má baà yàn egbé rè mébo.

- **Ìfanikalè:** Èyí ni ìgbésè fífa omo egbé kan kalè láti díje ìbò yòówù ó jé.

- **Asojú-dìbò:** Eni tí a yàn láti sojú egbé-dìbò tàbí se ìpinnu

- **Olùdìbò:** Eni tí ó dìbò tàbí tí ó ní ètó láti dìbò yan ni sípò tàbí s e ìpinnu.

- **Ètò ìforúkosílè:** Ìgbésè fífi orúko àwon tó tó ìbò dì sílè ni wóò dù kòòkan.

- **Àyèwò Olùdìbò:** Ìgbésè yíye orúko àwon olùdìbò wò ní ìbámù pèlú èrí láti inú ìwé ìforúkosílè olùdìbò.

- **Ibùdó ìdìbò:** Ibi tí a ti ń dìbò. Èyí gbódò jé ìbúdò tí olùdìbò ti forúko-sílè télè, àyàfi bí àjo tó ń mójútó ètò ìdìbò bá yè é lókù.

- **Yàrá Ìdìbò**: Ibi kólófin tí a yà sótò ni ibùdó ìdìbò níbi tí àwo n olùdìbò ti ń di ibo won lókòòkan

- **Ìbò bòńkélé:** Ìgbésè ìbò dídì tí ó jé alásìírí.

- **Ìbò Gbangba-làsá-ta:** Ìgbésè ìbò dídì tí ó jé pe gbangba ni a ti dì í. Lópò ìgbà ló jé wí pé níse ni àwon olùdìbò yóò tò séyìn omo egbé tàbí àwòrán eni tí won bá fé dìbò yàn.

- **Ìjoba Tiwa-n-tiwa:** Ìlànà ìjoba tí ó fàyè gba ará ìlú láti kópa té

rùn nínú ètò ìsèjoba. Irú ìjoba béè ń sàmúlò ìpinnu òpò ènìyàn nígbà tí àwon péréte jé alátakò. Ó see se kí ìjoba tiwa-n-tiwa má dára tán yán-án-yan-an sùgbón ìsòrí ètò ìsèlu tó dára ni.

- **Ètò-Ìsèlú:** Ètò ìsèlú jeyo nínú ìbásepò tí ó wà láàrin ìjoba àti àwon omo oríléèdè. Irú ìbásepò béè gbódò jé èyí tí ó dógba láàrin ètó omonìyàn àti ojúse rè. Ètò ìsèlú tún ní se pèlú ipò pínpín àti bí a se ń sàkóso búrùjí oríléèdè àti onírúurú ìsòro won. Ó se pàtàkì láti mò wí pé ìyàtò wà láàrin ètò-ìsèlú àti ìjoba.

- **Ètò-Ìsèlú Rere:** Àwon àbùdá Ètò-Ìsèlú rere kò pin sí orí àwon tí a óò dárúko wònyí nìkan sùgbón ara rè ni:

*Kíkopa, ìmúdúró, otito-inu, jíjábò isé ìríjú-eni, títònà àti níní-ìtéwógbà. Irú ìjoba béè máa ń fi òfin se fìtílà láti ríran fun ìsèjoba, won kìí sojú-sàájú tàbí fi òrò ako-n-bábo sègbè. Won a tún máa pèsè ohun amáyéderùn fún àwon ara ìlú.*

- **Ìjoba:** Ìlànà ìsàkóso-ìsèlú le àwon ènìyàn kan lórí nípa sísàmúlò òfin kí ààrin àwùjo baà lè wà ní ìrowó-rosè.

- **Ìsààlò:** Ìgbésè tí àwon ènìyàn tàbí ará ìlú ń gbé láti mú kí àwon tí wón wà ní ipo ase tàbí ìsàkoso ìjoba pèsè àwon ohun amáyé-de rùn kan tí yoo bá ìfé àkójopò àwon ará ìlú pàdé.

INSERT PIC

## 3. Àgbékalè Òfin tí ó níse pèlú Ìkópa Àwon Obìnrin Nínú Ìsèlú

Àwon àgbékalè òfin kan wa káàkiiri òde-àgbáyé tí ó fowó sí ìkópa àwon obìnin nínú ìsèlú.

### 3.1 Òfin Ìsèlú Ilè Nàìjíríà

Gbogbo obìnrin ni wón ní ètó pé a kò le yàn wón mébo ni gbogbo ònà títí tó fi kan ètó kíkópa nínú ìsè-joba lábé òfin-ìsèlú ilè Náìjíríà ti odún 1999; gégé bi omo oríléèdè. Irú àwon ètó béè nìwònyí.

Orí 11, Abala 15(2), 16(1b), 18(1) àti

Orí 1v, Abala 42(1) Abala 15(2)

Ní ìbámu pèlú ohun tí a ti wí, a óò tepele mó ìdàgbàsókè oríléèdè lápapò, a óò sì gbógun ti yíyan àwon ènìyàn kan mébo nítorí ìlú tí a ti bí won, àbùdá ako-m-bábo won, èsìn, ipò won láàrin àwùjo, èyá tí won jé tàbí èdè enu won.

**Abala 16(1b)**

Se ìsàkóso orò-ajé oríléèdè lónà tí yóò fi fi ìgbà de àwon ara-ìlú lórùn, tí won yóò wà ní gbedemuke nínú ayò àti ìdùnnú. Èyí yóò sì rí béè lábé ìdájó òdodo àti àye fifi-sílè fún ipò dógba-n-dógba àti àǹfààní láti ní ìdàgbàsókè.

Abala 42(1)

Omo-orile-èdè Nàìjíríà láti àwùjo kan, egbé ajemo-ìran kan, ibi orírun kan, ako-n-bábo, èsìn tàbí èrò ajemó-ìsèlú kan pàtó, nítorí kìkìdá pé ó je eni béè, kò níí

(a) ní ìrírí àìpé - ara tàbí ìhámó èyí tí àwon omo orílè-èdè Nàìjíríà ti àwùjo, egbé ajemo-ìran, ibi orísun, ako-n-bábo, è sìn tàbí èrò ajemó-ìsèlú mìíràn kò ní, pààpàá, yálà nípase tàbí ní mímúlò ní òtító, èyíkéyìí òfin tó wà ní lílo ní Nàìjíríà tàbí èyíkéyií isé afàsese tàbí isé ajemó-ìsàkóso tí ìjoba.

(b) ní ètó àrà-òtò tàbí àǹfààní tí a kò fún àwon omo orile-èdè Nàìjíríà ti àwùjo, egbé ajemó-ìran, orísun ibi, ako-n-babo, èsìn tàbí èrò ajemó-ìsèlú mìíràn, pààpàá yálà nípasè, tàbí ní mímúlò ní òtító, èyíkéyìí òfin tó wà ní lílò ní Nàìjíríà tàbí èyíkéyìí isé àfàsese tàbí isé ajemó-ìsàkóso.

Àwon abala òfin tí a menuba lókè yìí se ìtenumó ìlànà dógba-n-dógba fún gbogbo èdá ènìyàn àti àìse-ojúsàájú enikeni nínú gbogbo ìdáwólé omo ènìyàn pátà. Èyí wá fi hàn pé obinrin gégé bi èdá ènìyàn àti gégé bí omo oríléèdè ní gbogbo ètó gégé bi e lòmìíràn náà se ní in. Enikéni kò sì le dí i lówó láti jàǹfààni gbogbo àwon ètó náà nítorí kìkìdá pé ó jé obìnrin.

**Abala 39:** Ètó Láti fi èrò inú eni hàn

Gbogbo obìnrin tí ó bá jé omo oríléèdè Nàìjíríà ni ètó láti fi èrò

inú rè hàn. Ó sì tún létòó láti gbo ìròyín tàbí jírórò lórí rè. Bákan náà ni ó tún létòó láti dá ilé-isé ìgbéròyìn-jáde sílè.

**Abala 40:** Ètó Látí ni Ìpéjopò Àlàáfíà

Gbogbo obìnrin ló ni ètó láti bá àwon mìíràn sàpérò tàbí dara pò mégbé yálà ti òsèlú tàbí egbé mìíràn ti yóò bá sá ti se é lánfààní. Kò di dandan fún obìnrin láti gba ìyòǹda lówó enikéni kí ó tó s àmúlò àwon ètó yìí.

**Abala 41:** Ètó sí ìrìn-esè Aláìfòfin-ìjoba-dè

Obìnrin gégé bí omo oríléèdè Nàìjíríà ní ètó láti rìn láìfòfin dè jákè-jádò Nàìjíríà àti láti gbé ní ibi yòówu ó jé, béè ni kò sí omo oríléèdè Nàìjíríà tí a óò lé jáde ní Náìjíríà tàbí tí a óò ko ìwòlú fún sí ibè tàbí ìjáde lo kúrò ní ibè.

**3.2 Àgbékalè Ajo ilè Afrika Lorí Ètó Omo Ènìyàn**

Gbogbo àwon olórí orílè-èdè ilé Afrika tí won sì tún jé omo egbé ajo ènìyàn dúdú ni wón fi owó sí Àgbékalè ilè Afrika lórí ètó o mo ènìyàn nínú osù kefà odún 1981. Odún 1986 ni òfin yìí tó sès è wá di mímúlò. Ilè Nàìjíríà náà jé òkan lára àwon orílè-èdè tí ó fowó sí àmúlò[1] àwon àgbékalè náà. Àjo ilè Afrika yìí mò wí pé àìsójú-sàájú àti ìsòdodo jé òpá-kùtèlè fún omo orílè-èdè kòòkan láti kópa nínú ìsèlú. Díè lára kókó lára àgbékalè Àjo Ilè Afrika tó

[1]. ohun tí fifi owó sí àmúlò yìí ń wí ni pé oríléèdè kòòkan yóò fàyè gba àwon ìpinnu àjo wònyí ní oríléèdè rè.

so wí pé àwon obìnrin náà lè kópa nínú ìsélú nìwònyìí:

**Kókó-Ìpinnu 2** tó ní se pèlú àìsojú-sàájú: Won là á kalè láìrújú pé obìnrin kòòkan ní gbogbo ètó tí a ti ménubà, gégé bí ó se jé wí pé a kò gbodò déye sí obìnrin kankan nítorí àbùdá ako-n-bábo rè, tàbí èyà, egbé ibi, àwò, èdè, èsìn àti èrò ìsèlú tó ní tàbí èrò mìíràn ìbáà se ti orilè-èdè tàbí ti àwujo abínibí.

**Kókó ìpinnu 9** tóka sí ètó tó je mó lati gbo tabi mo  ìròyìn nipa ohun ti o n sele àti ìfi-èrò-inú-eni hàn. Omo Orílèèdè kòòkan ló ni ètó láti so èrò inú rè jáde lábé òfin.

**Kókó ìpinnu 10 ati 11** jé mó ètó tó rò mó kíkó-ara-eni-jo bí egbé àti ètó láti wà lájo-lájo. Eni kòòkan ló ní ètó láti dára pò mó e lòmìíràn bí ó bá sà ti setán láti bòwò fún àwon òfin inú egbé béè. Láfikún, omo orílèèdè kòòkan ló ni ètó lábé òfin láti dara po mó elòmìíràn kí won sì jo wà nínú àjo tàbí egbé kan náà.

**Kókó ìpinnu 13**  tóka sí ètó omokùnrin tàbí omobìnrin kòòkan láti kópa nínú ìsèlú orílèèdè rè kí irú eni béè sì lówó sí yíyan eni tí yóò máa se ìjoba lé won lórí.

**Kókó ìpinnu 28** Ojúse tó je mó Àìdéye-sí-enikéni
Èdá ènìyàn kòòkan gbódò bòwò fun enikeji rè irú ipò yòówù kí onítòhún ó wa láàrin àwùjo.

### 3.3 Ìpinnu Ajọ Àgbáyé Lórí Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn

Gbogbo àjọ àgbáyé fọwọ́ sí ìpinnu lórí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn nínú ìpàde gbogbo-gbòò tí ó wáyé ní ọjọ kẹwàá, oṣù kejìlá ọdún 1948. Ilẹ̀ Nàìjíríà náà fọwọ́ sí ìpinnu yìí gẹ́gẹ́ bí ọmọ ẹgbẹ́ àjọ àgbáyé yìí lẹ́yìn ìgbà tí wọ́n ti gba òmìnira ní ọjọ́ kìíní oṣù kẹwàá, ọdún 1960. Ọ̀kan nínú ohun tí ó ṣe pàtàkì nínú ìpinnu yìí ni wí pé ẹ̀tọ́ dọ́gba-n-dọ́gba ni ọkùnrin àti obìnrin ní sí àwọn ìdáwọ́lé ayé gbogbo tó fi kan ìpinnu ṣíṣe àti kíkópa nínú ọ̀rọ̀ òṣèlú. Àwọn kókó ìpinnu tí a fẹ́ mẹ́nubà ní ìsàlẹ̀ yìí tọ́ka sí èyí:

**Kókó ìpinnu 2 àti 7** tọ́ka sí ìpinnu àìdéye ṣénìkéni àti ẹ̀tọ́ ẹni kọ̀ ọ̀kan tó jẹ́ dọ́gba-n-dọ́gba lábẹ́ òfin. Kókó ìpinnu 19 ati 20 sọ̀rọ̀ nípa pé ọmọ orílẹ̀èdè kọ̀ọ̀kan ló ní òmìnira láti sọ̀rọ̀ inú rẹ̀ jáde. Bákan náà ní ó tún ní òmìnira láti darapọ̀ mọ́ ẹlòmìíràn kí wọn sì jọ wà pọ̀ bí ẹgbẹ́. Ní àfikún, kókó ìpinnu 21 fún ẹni kọ̀ọ̀kan ní ẹ̀tọ́ láti dá sí ọ̀rọ̀ ìṣèlú orílẹ̀èdè rẹ̀.

### 3.4 Àdéhùn Ọ̀de-Àgbáyé Lórí Ẹ̀tọ́ Ajẹmọ́-Ìṣèlú

Ìpàdé àjọ àgbáyé ló fọwọ́ sí àdéhùn lórí ẹ̀tọ́ ajẹmọ́ ìṣèlú yìí nínú ìpàdé wọn kan tí ó wáyé ní ọjọ́ kẹrìndínlógún oṣù kejìlá, ọdún 1966. Ó sì di mímúlò láti ọjọ́ kẹtàlélógún oṣù kẹta ọdún 1976. Ilẹ̀ Nàìjíríà náà fọwọ́ sí àmúlò rẹ̀ ní ọdún 1993. Díẹ̀ lára àwọn àdéhùn yìí tó ṣàtìlẹ́yìn fún àìdéye-sí-ẹnikéni àti àǹfààní dọ́gba-n-

dógba fún gbogbo èdá ènìyàn gégé bí ó se jé mó òrò òsèlú nìwò nyí:

**Kókó ìpinnu 2 àti 3** tí ó wà nínú àdéhùn náà ní se pèlú àìdéye-sí-enikeni àti ipò dógba-n-dógba láàrin okùnrin àti obìnrin pàápàá jùjo gégé bí ó se kan gbígbádùn ètó ìsèlú.

**Kókó ìpinnu 19 àti 21** inú àdéhùn náà tenu mó ètó eni kòòkan pé wón lómìnira láti so èrò inú won jáde, wón sì tún létòó láti kórajopò gégé bí egbé

## 3.5 Ìpàdé Lórí Dídá Owó Orísìírísìí iwa Ìrénije si Àwon Obìnrin Dúró

Ìpàdé àjo àgbáyé ló fowó sí ìdádúró orísìírísìí ìdéyé-sí-àwon-obìnrin nínú ìpàdé ojó kejìndínlógún osù kejìlá odún 1979. Ìpinnu yìí sì di mímúlò láti ojó keta osù kesàn-án odún 1981. Ile Nàìjíríà fowó sí ètó omonìyàn yìí gégé bí ó se je mo dídá owó orísìírísìí ìdéyé-sí àwon obìnrin dúró ni odún 1985. Àwon àgbékalè àdéhùn yìí sokùnfà ìdàgbàsókè àwon àdáwólé omo ènìyàn. Àwon ìtokasi ìsàlè wònyí gbé owó ìlànà ètó dógba-n-dógba fún àwon obìnrin sókè, pàápàá jù lo gégé bí ó se je mó ìpinnu síse nídìí ìsèlú:

**Kókó ìpinnu 2, 4 àti 15** tóka sí ìlànà àìdéye-sí àwon obìnrin, ìgbésè òdodo àti ètó dógba-n-dógba lábé òfin.

**Kókó ìpinnu 7** tenu mọ́ ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin láti kópa nínú ìṣèlú àti nínú ọ̀rọ̀ àwùjọ.

**Kókó ìpinnu 8** ní tirẹ̀ ni ìtọ́kasí ẹ̀tọ́ àwọn obìnrin ti ó jẹ́ dọ́gba-ń-dọ́gba pẹ̀lú ti àwọn ọkùnrin láti ṣojú ní oríṣìí àwọn ìpele ìjọba lóde àgbáyé àti láti kópa nínú iṣẹ́ yòówù tó jẹ mọ́ ètò àjọ àgbáyé.

## 4 Ìkópa Àti Ojúse Àwon Obìnrin Nínú Ìsèlú

Bí àwon obìnrin bá se kópa térùn tó nínú ìpele ìgbésè-ìsèlú kòòkan jé òpákùtèlè fún bí irú obìnrin béè se lè ní agbára òsèlú tó sùgbón sá, àwon ojúse kan dìrò mó àwon ètó ìsèlú wònyí. Bí àwon obìnrin bá sì kùnà láti se ojúse tiwon, dandan ni kí wón pàdánù àwon ètó ìsèlú náà; kò sì ní sí ààbò kankan fún won mó. Àwon ojúse àwon obìnrin gégé bí omo orilèèdè nìwònyí:

1. Wón le dibo funni, àwon náà sì lè gbápotí ìbò
2. Wón létòó àtibi àwon tí wón dipò òsèlú mú léèrè bí wón se ń sèjoba sí
3. Wón le kóra-jopò fún kíkópa nínú ìsèlú
4. Wón le topinpin tàbí kí wón se ìgbéléwòn fún isé-ìríjú àwon tó ń sojú fún won
5. Wón le darapò mó egbé òsèlú
6. Wón le làkàkà láti di ipò olórí mú nínú egbé òsèlú won

### 4.1 Ojúse Láti Dìbò Fúnni Àti Láti Gbápòótí Ìbò

Gégé bí omo orílè-èdè, obìnrin kòòkan ní ojúse láti dìbò ní àkókò ìdìbò léyìn ìgbà tí wón bá ti wè yan kàn-ìnkàn-ìn láti se béè . Bí àpeere, ojó-orí won, àti àwon àmúye mìíràn gbódò kún ojú

ìwòn. Ònà kan náà tí a fi lè ní agbára-ìsèlú kò ju nípasè ìlànà àpótí ìbò lo. Bí àwon obìnrin bá ti wá kùnà láti se àmúlò ètó won yìí, won kò hùwà bi omo orile-èdè gidi mó nìyen; won tí so ara won derú. Ó sì wá di kí àwon olósèlú máa dà wón kiri bí eran. Irú ohun tí ó bá wu olósèlú ni ó sì lè fi wón se, ibaa máà té àwon obìnrin wònyí lórùn. Ìdí wá nìyí tí ó fi ye kí àwon obìnrin náà pé ara won jo, kí won ó dúró déédéé, kí won ó sì fi ìmòran kun ìmòràn; kí won baà lè ní àseyorí rere.

## 4.2 Yíyan Olúdíje-ìbò

Ó se pàtàkì láti fi àwon kókó wònyí sókàn nígbà tí a bá fé yan olùdíje-ìbò

- Ìwà Oludije náà
- Àfojúsùn egbé-òsèlú tí olùdíje ti wá
- Àlàkalè isé-àmúse olùdíje fúnra rè (irú isé àmúse béè gbódò jé èyí tí yóò se àwon obìnrin àti àwon ènìyàn àwujo mìíràn láǹfààní)
- Dídára ònà-ìgbàsàkóso àwon adarí egbé
- Ìrísí egbé (ìlànà tí won ń télé, ipo tí wón to òrò ako-n-bábo sí
- Bóyá olùdíje ìbò tí yóò máa gbé ara rè sápamó léyìn ìbò

àti nígbà tó ba dé ipo ase ni tàbí kò ní se béè.

- Dìbò fún obinrin ti ó bá kun ojú ìwon.

## 4.3 Ìlànà Bí a se ń Dìbò

- Gbogbo omo-oríléèdè tí ó bá tó ìbò dì ló gbódò fi orúko sílè fún ìdìbò ni àkókò tí àwon àjo tó ń mójú tó ìbò bá yà sótò láti se béè. Wón sì gbódò gba káàdì ìforúkosílè fún ìdìbò.

- Gbogbo eni tí ó bá fi orúko sílè fún ìdìbò gbódò se àyèwò ìforúkosílè, kí won sì rí i pé kò sí sége-sège níbè

- Gbogbo olùdìbò (awon tí won ti fi orúko sílè láti se béè) ló gbódò farahàn ní ibùdó ìdìbò pèlú káàdì iforúkosílè won láàrin àkókò tí wón bá yà sótò láti se béè

- Olùdìbò kòòkan ló gbódò fi káàdì ìforúkosílè rè han akòwé ètò ìdìbò fún àyèwò kíníkíní

- Olùdìbò kòòkan ni àwon akòwé ètò ìdìbò yóò fún ní káàdì ìdìbò láti fi dìbò fún eni tí wón bá fé. Olùdìbò kòò kan yóò wá fika te àmì egbé tí ó bá fé. Ní bòńkélé ni èyí yóò selè (pàápàá jùlo nínú ètò ìdìbò bòńkélé)

- Olùdìbò yóò wá so káàdì ìdìbò sí inú àpótí ìbò tí a ti pèsè sílè.

- A gba olùdìbò ní ìyànjú láti rósè dúró léyìn ìgbà tí ó bá ti dìbò tàn tàbí kí ó padà wá láti wá jérìí sí ìyè tí àwon akò wé ètò ìdìbò bá ka àkójopò ìbò sí ní ibùdó ìdìbò won.

## 4.4 Ètó Àwon Obìnrin Nínú Egbé Òsèlú

Obìnrin náà ní irú ètó kan náà tí àwon okùnrin ní nínú egbé òsèlú. Irú ètó béè ni dídi ipò ìsàkóso mú nínú egbé. Irú ipo ìsàkóso béè lè jé:

- Olórí Egbé

- Alàgbà nínú Egbé

- Alábòòjútó Egbé

- Alága Egbé

*** kí àwon obìnrin wà nínú ìgbìmò tè-é-kótó inú egbé wúlò jú kí won jé èka kan lótò lo. Bí wón bá jé omo ìgbìmò tè-é-kótó, won yóò lómìiran nínú egbé, enikéni kò sì ní le tèwón mérè.*

## 5. Àwon Ìpèníjà To Dojú ko Àwon Obìnrin Nípasè kíkópa Nínú Ìsèlú

Akùdé ńlá ti dé bá òrò kíkópa àwon obìnrin nínú ìsèlú. Látodúnmodún ni àwon nǹkan tó fa iru ìpèníjà béè kò sé lára ètò-òrò ajé, àgbékalè àwùjo àti àmúlò àwon àsà kan tí ó dojú ko àwon obinrin gégé bi enikòòkan, eni tó ní ìdílé àti òsìsé ìjoba. Yíye àwon kókó wònyí wo fínní-fínní yóò wúlò fún bí àwon obìnrin se le kópa té rùn nínú ìlànà ìpinnu-ìsèjoba.

### 5.1 Àwon Ìdíwó Tó jemó Èrò Inú Àsà

Àwon ìgbàgbó ajemó àsà kan wa tó burú jáì tó ń di àwon obìnrin lówó láti kópa nínú ètò ìsèlú. Àwon ìdíwó béè ni:

- Àìlómìnira láti lo sí ibi tó wù wón
- Ìfi omobìnrin lóko ní kògbó-kògbó
- Yíyan àwon obìnrin nípòsìn gégé bí ìlànà àsà àti ìse se là á sílè (ara irú rè ni wí pé òbí a màa féràn láti bí omo okùnrin ju obirin lo, àǹfààní tó gbòòrò ló sì wà fún àwon omokùnrin láti di ipò òsèlú mú)

## 5.2 Àwon Ìdíwó tó jemó Ètò Orò-Ajé

- Òsì àti àìrísé-se

- Isé méta tí àwon obìnrin kànpò: Omo bíbí, owó wíwá àti ipa won mìíràn láàrin àwùjo

- Isé ilé (isé òfé)

- Àìríbi yawó sisé àti àìrówó-dókòwò

- Ojú sààjú òfin àwon òsìsé. Irú àwon òfin béè ni èyí tó de ìgbanisísé tí ó sì kan;

- dídá àti fifi orúko egbé òsìsé sílè
- ètó láti dara-pò mó tàbí jé omo-egbé osìsé kò dára tó
- àìgba àwon òsìse-bìnrin gégé bí asaájú egbé òsìs é. Òfin yìí ló fa ìdásílè kí egbe òsìsé ilè Naijiria ní èká egbé òsìsé-bìnrin lótò.

Gégé bí ìlànà egbé òsìsé òde àgbáyé ti wí, gbogbo egbe òsìsé elékùn-jekùn àti ti orílè-èdè kòòkan ló gbódò se ìdásílè èka kan tí ó je tobìnrin láti baà fi pàtàkì ètó àwon òsìsé-ilé hàn.

### 5.3 Àwon Ìdíwó tó je mó Ètò Àwùjo

- Ààbò èkó[2] nítorí àìsí-àǹfààní àti ìgbéláruge láti òdò àwon ènìyàn àwùjo

- Fífi òrò ako-n-bábo se òdiwòn ojúsààjú nínú ìgbe-ayé ojoojúmó. (èyí hàn nínú ipò àti àǹfààní tí kò tó nnkan tí àwon obìnrin ní.

- Ìpàdé òsèlú tó jé lóru-lóru-èyí ni síse ìpàdé ni àkókò tí kò fowò fún ni lóru wo ìdájí kùtùkùtù ojó kejì. Nítorí ètò tí ó rò mó bí a se ń pínsé ní ilè Nàìjíríà, púpò irú ìpàdé lóru-lóru béè ni àwon olósèlú ti ń se àwon ìpinnu pàtàkì-pàtàkì tí àwon obìnrin kìí sìí le yojú sí.

- Ìgbàgbó àwon ènìyàn ni pé òrò òsèlú tègbin-tìdòtí ni. Àwon obìnrin kìí le faga-gbága pèlú àwon okùnrin nídí òrò tó bá je mó tègbín-tìdòtí béè.

- Ìsolénu àti ìsonilórúko búburú a máa wáyé pààpàá jù lo bí a bá wo bí àwon oníròyìn se máa ń fé tanná wo ìgbésí-ayé lóko-láyà àwon òsèlú-bìnrin wò.

- Títúmò àwon ìwé èsìn lónà ti yóò fi yowó àwon obìnrin kúrò

---

2. Ekó wúlò púpò fún ìgbéláruge àti ìgboyà okàn fún àwon obìnrin. A óò sì rí wí pé níní-ìgboya nínú ara-eni jé òpákùtè lè fún ìdàgbàsókè àti kíkópa àwon obìnrin nínú ìsèlú.

nínú àwo-ìsèlú àti kúrò nínú ipò asèpinnu nípa ètò-ìjoba. Lópò ìgbà, àwon okùnrin náà ni wón wà nídìí ìsètumò awúrúju béè.

- Fífi ojú-sààjú mú kí àwon obìnrin pàdánù isé rere

- Àwon ènìyàn àwùjo tí kò mo rírì isé òòjó àìlówó-osù tí àwon obìnrin ń se.

## 5.4 Àgbékalè Ìlànà àti Àdáwólé Orílèèdè

- Orílèèdè a máa mò-ón-mò pá gígùnlé ìgbésè òdodo tì

- Àìjé kí àwon ìlànà tí àwon orílèèdè àgbáyé ń sàmúlò nípa ètó omonìyàn tó je mó àwon obìnrin rídìí jókòó ní ilè wa. Irú àwon ìlànà àgbáyé béè ni CEDAW, ACHPR, ICCPR àti UDHR

- Síso ìlú di tolóógun. Èró Ìjoba sojá tí kó sí àwon òdò lórí ní ilé ìwé, nínú ìdílé àti láàrin ile-isé ìjoba gbogbo. Èyí ló fa kí àwùjo má bìkítà fún ìgbé-ayé onídèra fún àwon obìnrin.

## 6. Ọ̀nà Àbáyọ fún Àwọn Ìpèníjà ti a ti Ménubà

Láti le borí àìdógba nídìí ọ̀rọ̀ àmúlò agbára àti ipò pípín tí ó wà láàrin àwọn ọkùnrin àti obìnrin èyí tó ń sàdínà fún àǹfààní àwọn obìnrin orílèèdè yìí. Àwọn ìlànà kan wà tí á lè sàmúlò fún ìgbéláruge àwọn obìnrin kí wón bàa lè kópa dáadaa nínú ètò ìsèlú. Díè lára irú ìlànà béè ni:

- Sísàmúlò àwọn ìlànà òde-àgbáyé tó ti wà nílè nípa ètó àwọn obìnrin, pàápàá jù lọ bí ó se kan ìkópa nínú ọ̀rọ̀ ìsèlú àti ìpinnu-síse. (irú ìlànà béè ni èyí ti a mò sí Ìgbésè Ọ̀dodo)

- Àtúnsè sí òfin ìsèlú àti òfin ìdìbò tí yóò se ìgbéláruge fún ìlànà dógba-n-dógba tí yóò sì lódì sí ojúsàájú.

- Àwọn àjọ tí wọn kìí se ti ìjọba gbogbo gbódò gùnlé ìdánilékòó tó ní se pèlú isé ará ìlú, Ìlànà ìròyìn, ètò-èkó àti ọgbón ìbánisọ̀rọ̀ láti baà ráyè ró àwọn obìnrin lágbára àti láti baà mú kíkópa wọn nínú ìsèlú jò geregere sí i.

- Ìpolongo láti òdò àwọn onílé-isé ìròyìn. Àwọn ilé-isé ìròyìn kò seé fọwó ró séyìn nídìí títan ìròyìn ká. Alájùmòsepò ni wón gbó dò jé nídìí ìgbéláruge kíkópa àwọn obìnrin nínú ìsèlú síse.

- Àgbékalè ìdánilékòó fún àwọn ọmọ egbé òsèlú gbogbo, àwọn tó ń wá ìbò àti àwọn èniyàn pàtàkì mìíràn nídìí òsèlú lórí ọ̀rọ̀ ako-n-

bábo.

- Àgbékalè ìdánilékòó fún àwon obìnrin tó ń du ipò òsèlú nípa àwon àmúye olórí. Irú ìdánilékòó báyìí yóò fí ojú ako-n-bábo wo ìpèníjà tó dojú ko àwon obìnrin. Yóò sì tún pé àkíyèsí sí í wí pe àjùmòse àti ìwà àìfi-ìhàlè pàse-wàá ni a fi le jé olórí rere.

- Gbígbógun ti ìwà ìfagídí-sójà-sèlú àti ìsèlú aláìmú-ìbò-lo. Irú èyí tí ó ti di bárakú fún àwùjo wa télè. Ònà tí a le gbà se èyí ni nípa síse ìdánilékòó tó je mó ìsèlú ní ilé-ìwé àti ní ilé isé ìjoba wa gbogbo.

- Ríró àwon obìnrin lágbára nídìí orò ajé nípa jíje kí won ní irú àǹ fààní kan náà sí: ètò-èkó, ìgbani-sísé, owó ìdókòwò, ati bee bee lo.

- Àwon olórí ìlú àti olórí elésìn gbódò fààyè gba jíjé kí àwon obìnrin di ipò olórí mú. Ònà láti se èyí ni pé kí won má máa s àgbékalè ìlànà àsà àti èsìn tí yóò fààyè gba ojú-sààjú

- Ìdánilékòó ajemó ìsèlú fún àwon abiléko àti omo-bìnrin.

## 7. Ìkádìí

Orísìírísìí ìdíwó ni àwùjo mò-ón-mò fi de àwon obìnrin kí èròǹgbà àwon okùnrin láti je gàba lé àwon obìnrin lórí bàa lè se. Èyí sì so àwon obìnrin di eni èyìn láàrin àwùjo. Sùgbón ká ma paró, àìnímò tó gbòòrò àwon obìnrin nítorí àwon ìdí ti a ti so sáájú ló sokùnfà kí èyí seé se. Gbogbo olólùfé nǹkan ire ló ni ipa pàtàkì láti kó kí irú ìdíwó béè baà le di àfiséyìn tí eégún fi aso àti kí a tó le rí ònà àbáyo tó seé fokàn tè.

Àwon obìnrin ní ojúse láti ró ara won lágbára nípasè liana ètò-èkó àti ètò orò-ajé kí won tó le borí àwon ìsòro wònyí. Ìdánilékòó tún gbódò wà fún àwon ènìyàn àwùjo láìdá eni kan sí lórí ìsepàtàkì ètó omonìyàn. Ìsòro kí àwon obìnrin má ní àǹfààní láti kékòó ìwé, òsì àti béèbéè lo, ló n sokùnfà àìdógba tó wà láàrin okùnrin àti obìnrin nídìí òrò ìkópa nínú ètò ìsèlú ti ó sì ń mú kí àìdógba yìí gbòòrò sí i.

Ó se pàtàkì fún ìjoba rere àti ìlànà ìsèjoba afìbòyàn láti mú ayé rorùn fún àwon obìnrin dé bi pé won yóò lè máa kópa nínú ètò ìsèlú ní ilè Nàìjíríà. Irú ìgbésè béè ni gbígbógun ti òfin tó ní se pèlú ojúsàájú àti ètò ìjoba oni-igbé-ayé tí kò fi tàwon obìnrin se. Ní àfikún, pípé tí àwon oloógun pé nínú ìsèlú ilè Nàìjíríà (èyí tí ràlè-rálè èrò àti ìlànà won sì tún ń bá wa gbé di bí a ti ń wí yìí) wà lára ohun tó ń pakún gbígbé àga àwon obìnrin séyìn agbo nígbà tí òrò bá kan ìgbésè láti sèpinnu tàbí sèjoba.

Bí a bá fé se àgbékalè àwùjo dógba-n-dógba tí kìí se olójúsàájú; níbi tí gbogbo omo oríle-èdè Nàìjíríà lókùnrin-lóbìnrin, tòdó-mo kùnrin àtòdó-mobìnrin yóò ti ní irú àǹfààní kan náà, a gbódò dá ìyàsótò nípa ako-n-bábo dúró. Ó sì tún gbódò yé wa wí pé àwùjo yóòwù tó bá ń dun àwon obìnrin ní ètó láti kópa nínú ìpinnu síse àti dídi ipò olórí mú, irú àwùjo béè ń pàdánù àwon nǹkan ribiribi lójúnà ìdàgbàsókè ìlú won ni.